*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n:*
*Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krísti gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krísti, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣ́ọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhinrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Ilẹ̀kùn Kan!



# JÉSÙ

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n:*
*Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krísti gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krísti, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣ́ọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhinrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Ilẹ̀kùn Kan!



# JÉSÙ

**Ǹjẹ́ o ṣì rántí?** Bí a ṣe ń sùn, tí à ń jí ni à ń súnmọ́ òpin àkókò wa lórí ilẹ̀-aiyé; ó sì ní ibi tí olúkúlùkù wa yóò wà, nígbẹ̀yìn. Ibi méjì péré ni ẹ̀dá-ènìyàn lè ti bá ara rẹ̀ lẹ́yìn ikú: Ọ̀run, tàbí ọ̀run àpáàdì. Ìrírí ayọ̀ tí kò lópin, àti ohun gbogbo tí ó dára ni ó wà ní Ọ̀run (Ìwé Ìfihàn 21:1-4). Àmọ́ ibi ìdálóró tí kò ṣeé fara dà ni ọ̀run àpáàdì jẹ̀ (Mátíù 13:41-42). Oró inú iná ọ̀run àpáàdì ni yóò jẹ́ ìdájọ́ fún ẹ̀ṣẹ̀ tí àwọn ènìyàn kọ̀ láti ronúpìwàdà rẹ̀, tí wọ́n sì kọ̀ láti wá ìdáríjì fún, lákòókò tí wọ́n wà láiyé.

Ẹnu Ilẹ̀kùn kan ṣoṣo ní a lè gbà wọ Ọ̀run. Ilẹ̀kùn náà ni Jésù Krístì (Jòhánù 10:9). Nípasẹ̀ Krístì nìkan ni a lè wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Ọlọ́run Bàbá (Jòhánù 14:6), tí a óò wá ní iyè àinípẹ̀kun. Bákan náà, nípasẹ̀ Jésù Krístì ni gbogbo ìlérí ìyanu tí Ọlọ́run Bàbá ṣe fún gbogbo ẹ̀dá ti ń ní ìmúṣẹ (2 Kọ́ríńtì 1 :20). Nípasẹ̀ Rẹ̀ ni à ń rí ìbùkún gbà (1 Kọ́ríńtì 8: 6). À ń rí ìbùkún gbà ní Orúkọ Jésù, nítorí pé Ọlọ́run Bàbá nífẹ̀ẹ́ àwọn tí wọ́n fẹ́ràn Ọmọ Rẹ̀, tí wọ́n sì gbàgbọ́ pé láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni Ó ti wá (Jòhánù 16:23-27). Èyí tí ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú gbogbo àwọn ìlérí Ọlọ́run Bàbá ni, ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ - èyí tí yóò wá sí ìmúṣẹ nígbà tí ènìyàn bá jọ̀wọ́ aiyé rẹ̀ fún Jésù Krístì. Àwọn tí wọ́n jọ̀wọ́ aiyé wọn fún un kì yóò dojúkọ ìdájọ́ láti wà nínú adágún iná. Wọ́n yóò ní iyè àinípẹ̀kun (Jòhánù 3:16).

Krístì pe gbogbo àwọn ọmọlẹ́yìn Rẹ̀ ní, *"Àgùntàn"* (Jòhánù 10:26-29). Òun ni *Olùṣọ́-Àgùntàn* àti *Ilẹ̀kùn* àwa àgùntàn Rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí *Olùṣọ́-Àgùntàn*: Ó ń ṣìkẹ́ wa, Ó ń tọ́ wa sọ́nà, Ó ń dáàbò bò wá, Ó sì ń pèsè fún wa (Jòhánù 10:7). Àgùntàn tí kò ní Olùṣọ́-Àgùntàn wà nínú ewu - kò ní áàbò! Yóò di ẹran ìjẹ fún àwọn ẹranko ẹhànnà àti àwọn apanijẹ mìíràn. Sátánì (kìnnìún tí ń ké ramúramù) máa ń wá àwọn tí ó máa jà lólè, tí ó máa pa, tí ó sì máa bà jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí *Ilẹ̀kùn*, Krístì ń pa àwa àgùntàn Rẹ̀ mọ́ kúrò lọ́wọ́ Sátánì àti àwọn ẹni ibi nínú aiyé tí ó ń lò láti ṣe iṣẹ́ ibi rẹ̀.

Ṣé ìwọ yóò ṣe ìpinnu láti gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ lónìí? Ó wá kí o lè ní ìyè, kí o sì lè ní i lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ (Jòhánù 10:10). Má ṣe rò ó láti sún Ọjọ Ìgbàlà rẹ síwájú. Ọ̀lá lè pẹ́ jù!

### Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

**Ǹjẹ́ o ṣì rántí?** Bí a ṣe ń sùn, tí à ń jí ni à ń súnmọ́ òpin àkókò wa lórí ilẹ̀-aiyé; ó sì ní ibi tí olúkúlùkù wa yóò wà, nígbẹ̀yìn. Ibi méjì péré ni ẹ̀dá-ènìyàn lè ti bá ara rẹ̀ lẹ́yìn ikú: Ọ̀run, tàbí ọ̀run àpáàdì. Ìrírí ayọ̀ tí kò lópin, àti ohun gbogbo tí ó dára ni ó wà ní Ọ̀run (Ìwé Ìfihàn 21:1-4). Àmọ́ ibi ìdálóró tí kò ṣeé fara dà ni ọ̀run àpáàdì jẹ̀ (Mátíù 13:41-42). Oró inú iná ọ̀run àpáàdì ni yóò jẹ́ ìdájọ́ fún ẹ̀ṣẹ̀ tí àwọn ènìyàn kọ̀ láti ronúpìwàdà rẹ̀, tí wọ́n sì kọ̀ láti wá ìdáríjì fún, lákòókò tí wọ́n wà láiyé.

Ẹnu Ilẹ̀kùn kan ṣoṣo ní a lè gbà wọ Ọ̀run. Ilẹ̀kùn náà ni Jésù Krístì (Jòhánù 10:9). Nípasẹ̀ Krístì nìkan ni a lè wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Ọlọ́run Bàbá (Jòhánù 14:6), tí a óò wá ní iyè àinípẹ̀kun. Bákan náà, nípasẹ̀ Jésù Krístì ni gbogbo ìlérí ìyanu tí Ọlọ́run Bàbá ṣe fún gbogbo ẹ̀dá ti ń ní ìmúṣẹ (2 Kọ́ríńtì 1 :20). Nípasẹ̀ Rẹ̀ ni à ń rí ìbùkún gbà (1 Kọ́ríńtì 8: 6). À ń rí ìbùkún gbà ní Orúkọ Jésù, nítorí pé Ọlọ́run Bàbá nífẹ̀ẹ́ àwọn tí wọ́n fẹ́ràn Ọmọ Rẹ̀, tí wọ́n sì gbàgbọ́ pé láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni Ó ti wá (Jòhánù 16:23-27). Èyí tí ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú gbogbo àwọn ìlérí Ọlọ́run Bàbá ni, ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ - èyí tí yóò wá sí ìmúṣẹ nígbà tí ènìyàn bá jọ̀wọ́ aiyé rẹ̀ fún Jésù Krístì. Àwọn tí wọ́n jọ̀wọ́ aiyé wọn fún un kì yóò dojúkọ ìdájọ́ láti wà nínú adágún iná. Wọ́n yóò ní iyè àinípẹ̀kun (Jòhánù 3:16).

Krístì pe gbogbo àwọn ọmọlẹ́yìn Rẹ̀ ní, *"Àgùntàn"* (Jòhánù 10:26-29). Òun ni *Olùṣọ́-Àgùntàn* àti *Ilẹ̀kùn* àwa àgùntàn Rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí *Olùṣọ́-Àgùntàn*: Ó ń ṣìkẹ́ wa, Ó ń tọ́ wa sọ́nà, Ó ń dáàbò bò wá, Ó sì ń pèsè fún wa (Jòhánù 10:7). Àgùntàn tí kò ní Olùṣọ́-Àgùntàn wà nínú ewu - kò ní áàbò! Yóò di ẹran ìjẹ fún àwọn ẹranko ẹhànnà àti àwọn apanijẹ mìíràn. Sátánì (kìnnìún tí ń ké ramúramù) máa ń wá àwọn tí ó máa jà lólè, tí ó máa pa, tí ó sì máa bà jẹ́. Gẹ́gẹ́ bí *Ilẹ̀kùn*, Krístì ń pa àwa àgùntàn Rẹ̀ mọ́ kúrò lọ́wọ́ Sátánì àti àwọn ẹni ibi nínú aiyé tí ó ń lò láti ṣe iṣẹ́ ibi rẹ̀.

Ṣé ìwọ yóò ṣe ìpinnu láti gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ lónìí? Ó wá kí o lè ní ìyè, kí o sì lè ní i lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ (Jòhánù 10:10). Má ṣe rò ó láti sún Ọjọ Ìgbàlà rẹ síwájú. Ọ̀lá lè pẹ́ jù!

### Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí: